# Isakoso Lori Ile (Earth Charter)

## Oro Asosaju

Awa ni akoko ti o lewu ni itan orile agbaye, akoko ti iran eniyan gbodo yan ojo iwaju won. Bi aye se n gbile ti o si n di nkan elege si, beni ojo iwaju wa kun fun ewu ati ileri. Lati tesiwaju, a gbodo mo pe laarin orisiirisii ise, iwa ati asa awa eniyan, idile kan na ni wa a si tun jo wa ni aye kan naa pelu ayanmo – ipin kan naa. A gbodo sowopo lati fayaran, ki a si se amojuto aye yi pelu ife ati ibowo fun eda ohun-kohun, eto awon eniyan, otito ati asa alafia. Nitori eyi, o se Pataki fun awa eniyan ti a wa ni aye, lati jo ni ajosepo ti o peye pelu gbogbo nkan elemi ati iran ti on bo ni ojo iwaju.

## Aye, Ile Wa

Iran eniyan je okan lara nkan ti o gboro lorile agbaye. Aye, ile wa, kun fun opolopo nkan elemi, alailegbe. Awon ipa adanida mu ki wa laye je nkan ti o lewu pupo, sugbon aye (ile) ti pese awon ofin ti o se Pataki fun orisi akoko. Iwa ni alafia gbogbo eniyan, eweko, eranko lorile aye daleri bi a se le se itoju tabi pa gbogbo nkan elemi, eweko, eranko, ile to lora, omi to mo, ati ategun alafia mo.

Gbogbo ayika aye ati gbogbo nkan ti o wa ninu re gbodo je nkan ti o je gbogbo eniyan logun. Abo fun aye, agbara iwa laye ati agbara lati mu iyato oniruru wa, je nkan ti o lowo ti a si fi le gbogbo eniyan lowo.

## Ipo Ti Aye Wa

Ona ti an gba da nkan sile ati ona ti a n gba je(run) awon nkan ni o mu iparun ba aye(ile), ifikan sofo ati iku opolopo awon eranko. A ko bikita fun

idagbasoke ati igberu agbegbe awon eniyan. A ko se olotito nibi pinpin oro ti ani ni orilede yii ni dogbandogba, bakan naa ni iyato to wa laarin mekunnu ati iwa ika n posi ni ojojumo, eyi ti o si n mu inira wa. Awon eniyan n posi ni orile aiye, eyi ti o mu ki gbogbo nkan se alaito fun wa. Eyi mu ki eru ki o wa , ti gbogbo nkan si wa ni ilewu.

**Ipenija**

O ku si wa lowo lati yan eyi ti a ba fe; yan lati dijo sowopo lati toju aiye(ile) ati omo enikeji wa, tabi ki a fi gbogbo re sile, ki a si wa ni ewu iparun ni ojo iwaju ati awa, ati awon nkan ti o wa ni aiye yii. A ni lati se awon atunse Pataki kan ninu iwa wa ati ninu gbogbo awon ile eko wa. A gbodo mo pe, niwonba igba ti a ba fi pese awon nkan ti o se koko, yio rorun fun wa lati yi awon eniyan pada si nkan ti o to. A ni imo ati oye lati mu iyipada ti o peye wa ni ayika wa. Idasile egbe ti o mojuto alafia eniayan, eranko, ile, ategun abbl, fun ni ore-ofe ati anfaani lati le ni, ati gbe igbe aye ti o peye ti o si kun fun aanu. Ayika wa, oro aje wa, eto oselu wa, ati isoro ti a ni nipa ti emi ni o dijo ni nkan se papo pelu arawon; ti a ba ni ifowo sowopo, A o dijo wa iladi si awon isoro wonyi.

**Ipa Ti Gbogbo Eniyan Gbodo Ko**

Lati rii pe amu gbogbo awon nkan wonyi wa si imuse, a gbodo pinnu lati gbe gege bi eni ti o ni ipa ti yo ko lori ile aye. Ki a fi ara wa jin, ki a si darapo mo awon nkan elemi ati alailemii, ti o wa lori ile aiye ni agbegbe wa ati gbogbo aiye pelu. Gbogbo wa ni a je omo orilede otooto, ti o n gbe ni orile aye, ti a si je ikanna ninu aye.

Gbogbo wa ni ipa ti a gbodo ko nisinsin yii ati ni ojo iwaju lori bi gbogbo iran eniyan yoo se wa ni alafia ninu aiye. Emi isokan awon eniyan ati ipo idari ti a wa yoo ni agbara nigba ti a ba se ibowo fun ati itoju awon nkan ti o lemi, mo pe eniyan ni ipa ti o gbodo ko ninu eda ohunkohun.

A nilo ni kiakia lati pin iran yii nipa bi a se le se itoju awujo eniyan, eranko, ati ohun ti o wa ni ayika wa pelu gbogbo eniyan. Nitori naa, ni ifowosowopo pelu ireti, a gba pe awon abuda wonyii ati awon nkan wonyii (ilana) yoo fun wa ni anfaani lati le se igbelewon ti o peye fun gbogbo eniyan, olu, ile ise, oro aje, ijoba ati gbogbo awon ile eko wa.

**I. Ibowo Fun Ati Itoju Awujo Nkan Elemi**

**1. Bowo fun aiye(ile) ati nkan elemi ni gbogbo ona**

a. Mo pe gbogbo eniyan ni o ni ajosepo, bakan naa nipe gbogbo nkan elemi ni o ni iyi ni ipo tire biotile wu ki eniyan se ro si

b. Ni igbagbo ki o si mo pe gbogbo eniyan ni o se Pataki ni ipo ati ona ti won yala ni.

**2. Se itoju awujo nkan elemi pelu oye, aanu ati ife.**

a. Gba pe bi o ti le je pe a ni ase ati ore-ofe lati le lo awon ohun adanida, bakan naa ni a gbodo ripe a dabobo awon nkan adanida yi. Bakan naa ni ki a bowo fun eto awon eniyan miran.

b. Se itenumo fun ominira, imo ati agbara bakan naa ni nki o ni ojuse fun itesiwaju nkan ti o dara.

**3. Ko awujo olominira ti o da lori otito, fun gbogbo eniyan ti o si wa ni alaafia.**

a. Rii pe gbogbo awujo wa ni idogba, ki won o si bowo fun eto ati ominira olukuluku ki won si fun olukuluku ni aanfaani ati le lo ebun re ninu ohun ti o le se.
b. Se igbaruku fun iwa otito ninu awujo wa, ti yo si fun onikalukuu ni aanfaani ati le gbe igbe aiye ti ko ni pa awujo ati gbogbo nkan ti o wa ni awujo lara.

4. **Bu ola ki o si se aye ni ewa fun iran ti o wa nisinsin yii ati iran ti o n bo ni ojo iwaaju.**
   a. Mo pe iwa ati ise iran kan, yoo ran iran ti o n bo ni ojo iwaju
   b. Ko awon iran ti o n bo ni eko lati mo iyi awon ohun adanida ati ohun elemi gbogbo.

Lati le se amuse awon nkan merin wonyi, o se Pataki fun wa lati:

## (II) Ajosepo Awon nkan elemi

5. **Dabobo isokan awon nkan elemi ati nkan adanida ti o wa lorileaye pelu ifiyesi Pataki fun eda ohun-kohun.**
   a. Gba gbogbo igbekale ati liana ti o n mu ki a se atunse ati idabobo gbogbo nkan ti o wa ni ayika wa, Pataki julo awon nkan elemi.
   b. Ki a se idasile awon ibi ti a ti le pese aabo fun awon eda ohun-kohun, koda pelu awon nkan ti o wa ninu isale omi ati gbogbo eranko ti o wa ninu igbo, ki a ba le dabobo eda ohun-kohun.
   c. Dabobo gbogbo awon eranko ti o wa ninu igbo ti a n pa ni gbogbo igba ti won si ti fere tan ninu igbo

d. Lo omi, ile, igi ati awon nkan ti o wa ni isale omi ni ona ti o to ti ko si ni mu ipalara ba aye ati awon nkan ti o wa ninu re.

e. Ki a se amujuto awon nkan alumoni ti o wa ninu ile bi epo pentiro ni ona ti ko ni mu ipalara ba orileaye ati awon nkan elemi lapapo.

f. Ki amojuto wiwa ati lilo ohun ti ko se dapada bi alumoni ati epo ti anri ninu ile ni ona ti ko ni je ki won tete tan, ti yo fi je ibaje si agbegbe wa.

6. **Idiwo fun ijamba/ewu gege bi ona Pataki ti ale gba dabobo awujo ati ayika wa, ti imo wa ko ba si to, e je ki a sora ki a si tele ilana ti o ba to.**

   a. Gbe igbese lati ri I pe a ko gbodo je ki awon nkan ti yoo tako alafia aye (ile) ati awon nkan miiran ko waye.

   b. Je ki o ye awon eniyan ti o n so pe awujo wa koni ni ewu kan kan koda bi a ko ba toju re ti a o si bikita fun. Je ki o ye won pe kori be.

   c. Ri i pe, awon ipinnu ti o ba yan yoo le mojuto nkan ti o n sele nisinsiyi, ati nkan ti o sese ki o sele ni ojo iwaju, bakun naa, o ye ki o ba aini gbogbo nkan elemi pade.

   d. Dina awon nkan aimo, ibaje tabi eri ti o le mu ijanba ba awon nkan elemi, alailemi, eweko, eranko ati gbogbo aye ni apapo.

   e. Yera fun awon apon tabi akan awon ologun ti o le mu ipalara ba ayika wa.

7. **Se awose ona ti a n gba bi, je/run ati ona ti a n gba tunmujade/ibi-si ti yoo dabobo ile ati ohun ti o wa ninu re, eto awon eniyan ati alafia ayika wa.**

    a. Din ku, ki o si tun se amulo awon nkan ati ona ti o gba se eeto mimu jade ati ona ti a n gba je, ki o si ri i pe awon eri naa ko pa ile lara.

    b. Ri i pe ti o ba n' lo nkan ti o ni se pelu ina manamana, se pelepele,a ti pe se ona bi wa se ma ri i ina yii lati inu agbara orun ati afeefe.

    c. Se igbekale eto ti peye ti o si muna doko lori awon ero igbalode ti o n' ma mu idera wa ni ayika wa.

    d. Ki aje ki adugbo wa ni owo si iye ti a diyele oja, ki awon alabara wa le mo iru oja ti yo wulo fun agbegbe wa.

    e. Ri i daju pe gbogbo eniyan lorileaye ni o ni eto ati anfaani si eto ilera ti yoo mojuto eto omo bibi.

    f. Gbe igbe aye ti yoo se itenumo igbe aye otun ati isepataki anito ati aniseku awon nkan ti a nilo lorileaye.

**(8) Se igbekale tabi iwadii eko nipa ayika wa ki o si je ki esi eko yii ati imo naa je lilo ni ayika wa.**

    a. Se agbateru fun awon orilede agbaye ti o n' se akoso ati iranlowo fun awon orilede keekeekee lori eto siensi.

    b. Mo ki o si dabobo awon imo atijo ati ogbon emi ninu gbogbo asa ti o n' dabobo ayika wa ati gbogbo eniyan

    c. Ri i daju pe awon eko Pataki nipa eto ilera, imo toto ayika ati eto ilera nipa omo bibi je imosi fun gbogbo ara ilu.

## I. Isotito Ati Idajo Ododo Ninu Ibakegbepo Ati Eto Isunna

**(9) Mu osi/ise kuro ni-ayika wa,**

a. Se onigbowo eto si omi mimu to dara, ategun alafia, ounje ti ko ni majele, ile ti o dara, ibugbe fun awon eniyan ati imototo ayika wa.

b. Ro awon eniyan ni agbara nipa imo ati eko lori bi won se le di eniyan gidi ni awujo, ati pipese awon obiriki fun awon ti ko ni ona ati ran ara won lowo.

c. Ranti awon ti a ko sile, dabobo awon alaini, pese fun awon ti iya n' je ki o si fun won ni ore-ofe ati le di nkan ti won fe da ni orileaye.

**10. Ri i daju pe eto oro aje wa ni gbogbo ona wa fun idagbasoke gbogbo eda ni dogbandogba.**

a. Se agbateru ona ti a o gba pin oro wa dogbandogba ni orilede wa ati laaarin orilede wa ati awon orilede miiran.

b. Se iranlowo pelu opolo, owo ati imo ti oni lati fi ri i pe orilede re ni itesiwaju, ki won si kuro ninu gbese.

c. Ri i daju pe gbogbo awon ona, ilana ati egbe pe oju osuwon ti won yoo le kopa ninu didabo bo ayika wa

d. Beere fun iranlowo awon ojulowo ile-ise nla lati kopa ninu pipese awon ohun alumoni fun awon eniyan.

**11. Se itenumo fun isotito ati idogba laarin Okunrin ati Obinrin gege bi ategun fun idagbasoke. Bakan naa, ri i daju pe gbogbo eniyan ni eto ati anfaani si ile-iwe, eto ilera ati eto oro aje.**

a. Ja fun eto awon obinrin ati omodebinrin, ki o o si dawo gbogbo iwa ipa duro

b. Fun awon obinrin ni aye lati kopa ninu oro aje wa, iselu ati asa wa, gege bi awon ti o ni anfaani lati le dari awon nkankan.

c. Gba awon idile ni iyanju ki o si rii daju pe won ni aabo ati alafia ti o peye

**12 Se atileyin fun eto gbogbo eniyan, lai si ojusaaju, darudapo tabi eleyameya. Bakan naa, ki a bu ola fun eto awon onile ati awon eko won.**

a. Doju ija ko iwa eleyameya ni gbogbo ona, papa julo eyi ti op ni se pelu ede, eya, awo, ako tabi abo, esin, abbl.

b. Se agbateru eto awon omo onile lori nkan ti won gbagbo, imo, ile, ati awon nkan miiran.

c. Bowo fun awon omode ti won wa ni ayika wa kii osi ti wonleyin lati je eniyan Pataki ninu awujo ati agbegbe wa.

d. Dabobo awon nkan ayika wa, Pataki julo awon ibi ti o nise pelu asa wa ati nkan ti a gbagbo.

**IV. ETO OSELU, AISI ROGBODIYAN ATI ALAFIA**

**13. Se atileyin fun eto oselu, ki awon aladari si je olotito, ki a si ni anfaani si idajo ododo.**

a. Se atenumo fun eto ki onikaluku ba le ni anfaani si irohin nipa ayika, nkan ti o le koba ayika wa ati ona ti a le gba dabobo ayika wa.

b. Gbaruku ti awon elegbejegbe ati awon eniyan ti o wa ni ayika wa ati ni ibo miran lati kopa ninu imoran ati liana ti yoo mu itesiwaju wa.

c. Dabobo eto awon eniyan lati so nkan ti o je won logun, eto won lati pe jo ati eto lati beere nkan ti o to si won.
d. Se idasile eto tabi ilana ti yoo fun awon eniyan ni anfaani lati le lo si ile-ejo, ki won si ri idajo ododo gba lori nkan ti o ni se pelu ayika ati ile
e. Dekun iwa ibaje ni aarin awon osise ati awon ti won wa ni ijoba
f. Gba awon adugbo ati agbegbe keekeekee ni iyandu lati ma toju ayika won, ki awon eka ijoba naa si ni ipa ti awon naa yoo ko ninu eto yii.

**14. Ko awon akekoo ni ile-eko ni ogbon ati oye bi won sele gbe igbe aye ti o peye**

(a) Fun gbogbo eniyan, Pataki julo awon omode ati odo ni anfaani lati lo si ile-iwe ki won ba le lo imo ati eko naa fi tun ilu se

(b) Se agbateru orisii eko ni ile-iwe, bi eko siensi ati eyi ti o ni se pelu awon eniyan eyi ti yoo si fun awon akekoo ni imo ti o jinle.

(c) Je ki awon eniyan mo iwulo ati ipa ti redio, telifisan ati iwe iroyin ko ninu bi a se le toju ayika wa.

(d) Je ki awon eniyan ko mo iwulo esin ati eko-ile fun igbe aye ti o dara.

**15. Huwa si gbogbo eniyan pelu ibawo ati ifiyesi**

a. Dabobo bo gbogbo awon eran osin ti o wa ni ayika wa, ki o si ri i pe o fiya jewon.
b. Dabobo awon eran igbe lapapo, nipa ki o mase je ki awon olode tabi apeja pawon ni ona ti ko to, ti o si le fa iku oro fun awon eran igbe tabi eja wonyi.
c. Mase je ki awon eniyan pa awon eranko ni ona ti ko to.

**16. Se atenumo fun iwa ifarada, aisi rogbodiyan ati alafia**

a. Gba awon eniyan ni iyanju lati gbe ni igbe alafia, ifowosowopo ati isokan ni orilede wa ati pelu orilede miiran.

b. Lo awon ilana ti o peye ti o si to lati fi da rogbodiyan duro laaarin awon eniyan, ki o so lo ilana ti o to lati fi mu ija ati rogbodiyan kuro ni ayika wa.

c. Gbiyanju lati rii pe a mu ise ati isin awon ologun role ni ile wa nipa gbigbe ni alafia laarin ara wa ati ni ayika pelu

d. Mu awon ohun ija olooro kuro patapata

e. Ki aripe ohun elo sanmo ati oju orun fi ara mo idabobo adugbo ati alafia.

f. Mo pe a le gbe ni alafia nigba ti a ba jo ni asepo ti o dara pelu ara wa, awon elomiiran, awon asa miiran ati ile, nitori pe, gbogbo re won nu ara won.

**Ona Abayo**

Bi o ti le je a o ri ninu itan, o se Pataki fun wa ki a bere si ni gbe igbe aye otun. Iru igbe aye otun yii ni ileri ati ilana ti Earth Charter gbe wa fun wa lati mu ileri yii se, a gbodo fi ara wa jin ki a si wa ilosiwaju iyi ati erongba egbe yii.

Eyi tumo si pe, a gbodo yii ero okan wa pada si ohun ti o to, ki a si je eniti gbogbo aye le gbekele. A gbodo ni iran fun ojo iwaju ti yoo fun awon eniyan wa ati gbogbo agbaye ni ore-ofe ati gbe ni igbe alafia. Bi o tile je pe awon asa wa yato si ara won, sibe a le jo pin ninu iran ojo iwaju yii. A gbodo se agbateru

fun eto yii, ki a si mu opolopo eniyan lorileaye aye mo nkan ti (Earth Charter duro fun, nitori pe, opolopo nkan ni a o ko, ti yoo si fun wa ni ogbon ati otito.

Nigba miiran, o ma n'soro fun wa lati yan ninu awon nkan ti o ba se koko tabi Pataki ti o ye ki a se. Sugbon , a gbodo wa ona lati ri i pe a di okanna, ki isokan ba le wa, ti yoo si mu alafia wa. Gbogbo eniyan, idile, egbe, adugbo,awujo ati agbegbe ni o ni ipa Pataki lati ko. Gbogbo awon onimo ona ise, awon onimo siensi, esin, awon ile eko, awon onisowo, awon onise adani ati ijoba lapapo ni a n' pe lati wa dari eto yii. Ifowosi ijoba, awon eniyan ati awon onisowo se Pataki fun idari ati isakoso ti o peye.

Ti a ba fe ki gbogbo eda o wa ni isokan, gbogbo orilede aye gbodo fi ara won jin fun agbajopo orilede gbogbo agbaiye (UN) ki a tele ofin ati liana won gbogbo labe ofin, ki a si fowosowopo pelu Earth Charter lati tele ofin won ti se: sise alamojuto ayika wa ati itesiwaju eda gbogbo.

E je ki a ranti igba wa si rere nipa titoju ati bibu ola fun ayika wa ati awon nkan elemi. Ki a duro fun isotito/isododo, alafia ati' ayo wiwa ni aaye.